# ÀÀBÒ ATI AYỌ̀ OLODODO

## Orin Dafidi 91:1-16

## ẸKỌ 83 -- FUN AWỌN ỌDỌ

**AKỌSORI: "Iwọ li àbo ati odi mi; Ọlọrun mi, ẹniti emi gbẹkẹle" (Orin Dafidi 91:2).**

### Ibugbe Wa

Ọpọ awọn ti o fẹ ki awọn ileri inu Saamu ti a mọ̀ daradara yii ṣẹ si wọn lara ni wọn ti kà á. O ni ipò kan ti eniyan ni lati wà ki eyi to le ri bẹẹ. O wa ninu ẹsẹ kin-in-ni, eyi ti o jẹ kókó ti iyoku Saamu yii gùn lé. Ki a to le gbé ni abẹ́ ojiji Olodumare o ṣe danindanin pe ki a jokoo ni ibi ikọkọ Ọga Ogo. Ọkàn ti o ba jokoo ninu Ọlọrun ni o wà lailewu kuro ninu ibi gbogbo.

Koko pataki ni ọrọ yii "joko" jẹ. Lati jokoo ni lati ni ibugbe kan ti o daju ati lati maa wà nibẹ. A ni lati ni ipinnu lati maa wà ninu Oluwa nigba gbogbo, lati maa wà nitosi Oluwa – ki i ṣe lati ni ayé diẹ ati Ihinrere diẹ -- nitori Bibeli sọ fun ni pe awa ko le "sin oluwa meji." Itumọ jijokoo ninu Ọlọrun ni pipinya patapata pẹlu ayé, ki a má tilẹ tẹ̀ diẹ si i. A kò le wà fun Oluwa fun igba kan ki a si ṣe bi a ti fẹ ni igba miiran. Lati joko ninu Oluwa ni lati maa ṣe ohun ti o tọ́ lojoojumọ ati lati maa wà ni ọgangan ifẹ Rẹ̀ ni igba gbogbo (Orin Dafidi 106:3).

Ki awọn Ọmọ Israẹli to wọ inu ilẹ Kenaani, wọn kọkọ rán awọn ami kan lọ si ilu Jeriko. Wọn dé si ile Rahabu, ẹni ti o fi wọn pamọ kuro loju ọba ti o si ràn wọn lọwọ lati sá lọ nipa sisọ̀ wọn kalẹ lori ogiri. Nitori o ṣe eyi o beere pe ki awọn Ọmọ Israẹli naa fun oun ni aami pe wọn o dá oun sí nigba ti wọn ba pada wá lati gba ilu naa. Awọn ami naa wi fun un pe ki o so okùn ododo naa mọ́ oju ferese, nipa eyi ti o fi mu wọn sọkalẹ lori ogiri naa. Wọn kilọ fun un pe o ni lati jokoo ninu ile naa ti a so okùn ododo mọ́ ferese rẹ̀. Bi o ba jade kuro ni ile naa nigba ti wọn ba pada wọn kò ni dá a si. O ni lati jokoo nibẹ nigba gbogbo. Bakan naa ni lọna ti ẹmi, niwọn igba ti ẹni kan ba wà ninu Oluwa ti o si jokoo labẹ aami Ẹjẹ naa – eyi jẹ pe a ti gba a là -- apa ayeraye Rẹ̀ yoo ṣiji bo o.

### Aabò Wa

Orin Dafidi yii lodi pupọ si awọn aabo ayé. Ọpọ eniyan ni wọn n fi igbekẹle wọn sori nnkan ti igba isisiyii ti n ṣegbe. Boya eyi ti o leke ninu awọn iru nnkan bẹẹ ni owó, ṣugbọn awọn ti wọn ni in lọpọlọpọ ti ri pe kò lagbara lori aisàn tabi àjálù. Bẹẹ ni kò le ra anfaani fun eniyan lati de Ọrun. Ninu I Timoteu 6:10, a kà pe, "ifẹ owo ni gbòngbo ohun buburu gbogbo." Bibeli tun sọ pe igba yoo de ti "enia yio jù òriṣa fadakà rẹ̀ ati òriṣa wurà rẹ̀…. si ekute ati si àdan" (Isaiah 2:20).

Awọn ẹlomiran ro pe awọn wà lailewu pẹlu iwe mimọ̀ tabi ohun ijà. Kò si eyikeyi ninu nnkan wọnyii ti o le fun ni ni aabo ti o daju. Ki ni awọn eniyan yoo si rọ̀ mọ́ ni ọjọ ti "Ọrun on aiye yio rekọja"? (Marku 13:31). Igbẹkẹle ati ifọkanbalẹ Onigbagbọ wà ninu Oluwa, odi rẹ̀ ati oludasilẹ rẹ̀ nigba gbogbo ati ni ayeraye.

### Aabò ati Olugbala Wa

Dafidi mọ̀ bi o ti ri lati sá àsálà fun ẹmi rẹ̀ nitori Saulu gbiyanju lati pa a. Ninu Orin Dafidi kejidinlogun ẹsẹ keji (18:2). Dafidi ni ẹri kan naa: "OLUWA li apáta mi, ati ilu-olodi mi, ati olugbala mi: Ọlọrun mi, agbara mi, emi o gbẹkẹle e; asà mi ati iwo igbala mi, ati ile-iṣọ giga mi"; nitori o mọ̀ pe ọwọ́ Ọlọrun ni o ti gba oun là. Onigbagbọ a maa ri ohun gbogbo ti o n fẹ ninu Oluwa; ṣugbọn ẹlẹṣẹ a maa tẹ̀ si imọ ara rẹ̀ ti o lọ si ibi iparun.

Ọta tilẹ le dẹ okùn fun ẹsẹ̀ rẹ, ṣugbọn "olododo li Ọlọrun, ẹniti kì yio jẹ ki a dan nyin wò jù bi ẹnyin ti le gbà; ṣugbọn ti yio si ṣe ọna ati yọ pẹlu ninu idanwò na" (1 Kọrinti 10:13).

Ki i ṣe pe Ọlọrun yoo gbà wá nikan ṣugbọn yoo daabo bo tabi ṣiji bò wá. Aabò yii tilẹ nipọn ju bẹẹ lọ, nitori aabo naa ti wà ki a to maa wá idasilẹ. Oun ni aabò wa. Nigba ti Jesu n sọrọ nipa Jerusalẹmu O wi pe Oun i ba fẹ radọ bo awọn ọmọ rẹ̀, bi agbebọ ti i radọ bo awọn ọmọ rẹ labẹ apá rẹ. Jesu lo apeerẹ yii lati fi ifẹ, itura, aabò ati ifọkanbalẹ ti o wà ninu Oluwa hàn. Oun jẹ́ ibi-isadi nigba gbogbo: "Nitori on tikalarẹ ti wipe, Emi kò jẹ fi ọ silẹ, bẹni emi kò jẹ kọ ọ silẹ" (Heberu 13:5).

### Iparun Wa

Lasiko Ogun Ajakaye keji, ailonka awọn ọdọmọkunrin ni o ka Saamu kọkanlelaadọrun (91) ti a n pè ni "Saamu Atukọ." Wọn kò ka a nikan, ṣugbọn wọn gba a gbọ́ wọn si dan an wò pẹlu. Bi o tilẹ je pe awọn eniyan n ṣubu lẹgbẹ wọn, ọpọ awọn ti wọn gbẹkẹle Oluwa ni wọn bọ́ lọwọ ikú, awọn miiran kò tilẹ fara pa rara.

Bakan naa ni awọn ileri wọnyii jẹ́ otitọ ni akoko alaafia. Fun awọn ẹni igbala, ileri wà pe ibi kan ki yoo ba wọn, ajakalẹ-arun kankan ki yoo si kọlu wọn. Nigba ti a darukọ ajakalẹ-arun, a ranti awọn ajakalẹ arun mẹwaa ti o wá sori awọn ara Egipti. A rán iṣẹlẹ buburu wọnyii si wọn nitori wọn kọ̀ lati gbọ́ ti Ọlọrun. Ki i ṣe awọn eniyan naa nikan, ṣugbọn ilẹ naa paapaa ni Ọlọrun fi ọwọ le. A ranti pe, nigba ti awọn arun naa bẹrẹ si le si i, Ọlọrun paala si aarin Egipti ati ilẹ Goṣeni nibi ti awọn eniyan Rẹ̀ n gbé. Awọn arun naa bo ilẹ titi dé etí ilẹ Goṣeni, ṣugbọn wọn kò wọ inu rẹ̀. Ọlọrun kò ni ṣe dinku lonii fun awọn ti wọn ba gbé ọkàn wọn le E.

### Aṣẹ nitori Rẹ

Ọlọrun ti pese awọn ẹmi ti o n jiṣẹ fun awọn ti yoo jogun igbala, lati maa ṣẹṣọọ lori wọn (Heberu 1:14). Ero yii ni a ti fi hàn kedere ninu aworan kan ti apele rẹ̀ n jẹ́, "Angẹli Oluṣọ," eyi ti o fi angẹli kan hàn bi o ti n ṣọ́ awọn ọmọde meji ti n rin kọja lọ lori afara kan ti o lewu. Aworan yii ti jẹ orisun igbagbọ́ ati ireti fun ọpọlọpọ. Awọn ọmọde ati agbalagba lo fẹran rẹ̀, nitori nipasẹ rẹ̀ igbẹkẹle ti dipo ifoya.

Olukuluku ọmọ Ọlọrun ni angẹli Oluwa ti daabo bo. Wọn le ri bi ọwọ Oluwa ti gbà wọn ni akoko ewu, ninu ohun ti o tobi ati omiran ti o kere. Nigba pupọ ni wọn ti ni iriri aabo nipasẹ odindi Bibeli, tabi apa kan rẹ tabi iwe miiran lori ẹkọ Kristi, tabi adura.

Apa kan ninu Saamu yii ni eṣu mu lo nigba ti o dán Jesu wò. O gbe E le ṣónṣo Tẹmpili, o si wi pe, "Bi iwọ ba iṣe Ọmọ Ọlọrun, bẹ́ silẹ fun ara rẹ lati ihinyi lọ: a sá ti kọwe rẹ̀ pe, "Yio paṣẹ fun awọn angẹli rẹ̀ nitori rẹ, lati ma ṣe itọju rẹ: ati pe li ọwọ́ wọn ni nwọn o gbé ọ soke, ki iwọ ki o má ba fi ẹsẹ rẹ gbún okuta" (Luku 4:9-11). Eṣu le ka Iwe Mimọ́, ṣugbọn nihin yii, gẹgẹ bi o ti maa n ṣe nigba gbogbo, o ṣi i sọ tabi o ṣi i lò.

Jesu fesi fun un nipa idahun yii pe, "A ti sọ pe, Iwọ kò gbọdọ dán Oluwa Ọlọrun rẹ wò." Gẹgẹ bi Jesu ti gbọran si ọrọ wọnni, bẹẹ ni a ni lati gbọran si wọn lonii. Ninu Orin Dafidi kọkanlelaadọrun (91) a kà pe Onigbagbọ le fi ẹsẹ tẹ kiniun tabi ejò lai si ewu. Ṣugbọn oun kò ni mọọmọ ṣe bẹẹ ki o ma ba dán Ọlọrun wò; bẹẹ ni oun ko jẹ ṣe nnkan elewu miiran ti yoo jẹ́ ikugbu si Ọlọrun.

**Fẹ́ Ifẹ Rẹ si I**

Saamu kọkanlelaadọrun yii le jẹ ẹri ti rẹ pẹlu. Fun ẹni ti o fẹ́ ifẹ rẹ̀ si Oluwa, O ti ṣeleri igbala ni akoko ipọnju ati idahun nigba ti o ba pe. Ninu Isaiah 65:24 a sọ fun ni pe, "Yio si ṣe, pe, ki nwọn ki o to pè, emi o dahùn; ati bi nwọn ba ti nsọ̀rọ lọwọ, emi o gbọ́."

O ṣe danindanin fun ọ lati fi Oluwa ṣe ibujoko rẹ ki o ba le gba awọn ileri wọnyii. Diẹ ni Oluwa n beere lọwọ rẹ ni idapada ninu ọpọlọpọ nnkan ti O n fi fun ọ. Ninu Mika 6:8 a kà pe: "Ohun ti OLUWA bère lọwọ rẹ, bikoṣe ki o ṣe otitọ, ki o si fẹ ãnu, ati ki o rìn ni irẹ̀lẹ pẹlu Ọlọrun rẹ?"

**AWỌN IBEERE**

1. Ta ni a ṣe awọn ileri inu Saamu yii fún?
2. Bawo ni a ṣe le mọ̀ pe a jokoo ni ibi ikọkọ Ọga-Ọgo?
3. Bawo ni Oluwa ṣe jẹ́ odi wa?
4. Ki ni asà ati apata wa?
5. Ta ni a fun ni aṣẹ lati maa ṣẹṣọọ lori awọn eniyan mimọ́?
6. Ki ni itumọ didán Ọlọrun wò?
7. Ka iwe itankalẹ Ihinrere pẹlẹbẹ kọkanla ti Ijọ Igbagbọ́ Apọsteli ti akọle rẹ̀ jẹ́ "Saamu Atukọ"